# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LA WA

No. 580 WEDNESDAY APRIL, 15 1964 (2D)


## Ijamba Ina Nla Kan Ṣẹlẹ L'Eko

EKO:— Gbogbo ilu lo gbojikan fun ariwo ti idaamu nla si ba gbogbo awọn ara adugbo nigbati ina nla kan ṣẹlẹ ni adugbo Onilẹgbalẹ ni agbegbe Isalẹ Eko ti ile mẹwa si jona tan raurau ni opin ọsẹ ti o kọja yi.

Nkan to si fa ijamba ina na ni ẹnikan to ndin ẹja ni deede agogo mẹrin abọ ti ko ran ti lati pa ina ti o fi ndin ẹja na.

Ninu awọn enia ti ina na ṣẹlẹ sile rẹ si sọ fun Onirohin wa pe gbogbo ero ọkan on fun ileya ti parẹ nitori pe gbogbo awọn ohun ti on ni si ti ba ina lọ.

Ọgbẹni Ishọla Fẹhintọla ti oṣe iṣẹ ni ile iṣẹ awọn oni Siga ti ngbe nọmba 17 Onilẹgbalẹ gun oke lọ ninu ina na fun awọn ohun ini rẹ to ṣegbe sinu ina.

Ọgbẹni Ishọla sọ pe eyi ni awọn nkan ti on ni Dansiki ati awọn Sokoto o si tun sọ fun Onirohin wa pe on na ni on yio ma lo titi ipari oṣu, ti on ba gba Owo oṣu, on yio lọ sare ra awọn aṣọ ti on yio ma a lo.

X Ina omiran tun fẹ ṣẹlẹ ni o p o p o Luther bakanna ohun to si tun fa eyi ni ina Ẹlẹntiriki to si Ṣana lojiji ti o si gba ina, Ṣugbọn a w ọ n panapana tete de, nwọn si pa ina na lẹsẹkẹsẹ.

## Agbẹjọro Awolọwọ Kilọ Fun Adajọ

# OLEARI ATI OBỌH KI IṢE ẸLẸRI ODODO

EKO:- Gbogbo Ile ẹjọ gigajulọ fun Orilẹ-ede Naijiria palọlọ ti ẹnikẹni ko si sọrọ nigbati Ọgbẹni Victor Duiand, Agbẹjọro Oloye Awolọ-wọ̄nsọ fun Ile-ẹjọ ninu kotu ni ana pe, Ọgbẹni Henry Oleari ati Anthony Obọh ti nwọn wa jẹri ninu Ile-ẹjọ giga ti Ọgbẹni Ṣowẹmimọ fi ju Oloye̊Awolọwọ sẹwọn ko to tẹle, ẹri wọn ki isi ṣe ẹri ododo.



G. S. Ṣowẹmimọ

Lẹhin eyi ni o wa rọ adajọ pe, ki nwọn tẹle on kalọ ki awọn jijọ yẹ akọsilẹ ẹjọ ti awọn enia na ro wo.

O ṣe alaye pe gẹgẹbi iwe ti Oloye Anthony Enahoro kọ si Oloye Awolọwọ, o mbere lọwọ Oloye Awolọwọ, pe, Oleari wa si ẹdọ on, ṣe ki on san owo fun un, ti o ba si jẹ be ẹ, elo ni ki on san ?

O wa bere pe, "kini ohun ti o jọ ohunti nwọn pe ni idoju Ijọba de ninu ohun ti o wa ninu iwe yi ?"

Anthony Oboh tun sọ fun ,Ọgbẹni Jakande pe on ko ni itẹlọrun si nigbana ti on lọ ṣugbọn awọn enia ko gba fun on lati ma lọ.

O si tun fi ẹnu ararẹ sọ niwaju adajọ pe, nwọn fun on ni adọta pọnun (£50) nwọn si sọ fun on pe ki on ma a lọ si Uromi ki on, lọ simi fun ọjọ mẹrin.

"Ti a ba fi oju inu wo ẹjọ awọn enia mejeej̄ yi, Oleari ati Obọh, ẹo ri wipe ẹjọ ti awọn mejeeji wa ro fun ile ẹjọ ya tọ si ara wọn, eyi si fi han pe, ẹri eke ni nwọn wa jẹ ni ile ẹjọ."

Ṣibẹsibẹ na, awọn ẹlẹri na ko da Orukọ Awolọwọ ninu ẹjọ wọn, Jakande ati Enahoro ni nwọn darukọ, o wa bere pe, "kini Awolọwọ ṣe ti o fi jẹbi ?"

Ọgbẹni Durand tun ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe, Rogbodiyan kan ni o bẹsilẹ ni Ipinlẹ Agbedemeji ni agbegbe Ishan ti Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre kan ku ninu ija na.

O ni eyi lo fa, ti Ọrẹdein ati Jakande fi lọ si Ipinlẹ na pẹlu



Oloye Awolọwọ

awọn akọwe ẹgbẹ ti nwọn ti kọ ni Ọna iṣẹ akọwe.

Nigbati o di ọjọ kẹrinlelogun oṣu keje ọdun 1962 ni Ijọba tu Oloye Enahoro silẹ ninu ofin pajawiri.

Bi o ti nsọrọ lọwọ ni Ọgbẹni Adedipẹ ba dide ti o si yọ ẹda iwe ti Oloye Enahoro kọ si Awolọwọ.

Ọgbẹni Adedipẹ ṣe alaye pe, nigbati awọn gba lẹta na lọwọ Oloye Awolọwọ, awọn fi ranṣẹ si Oloye na pada, ṣugbọn ko ri lẹta na gba, ẹda iwe na niyi.

Ohunti ti o mu Adedipẹ fi ṣe alaye yi ni, ọrọ ti Agbẹjọro Oloye Awolọwọ sọ pe, ọrọ na wa ninu iwe idajọ ṣugbọn Ijọba gba iwe na lọwọ Awolọwọ nwọn ko si dapada fun un.

Lẹhin eyi ni awọn adajọ gba ẹda lẹta na yewo, nwọn si fun Ọgbẹni Adedipẹ ni iwe na pada.

Ọgbẹni Durand ni adọta pọnun (£50) ni Jakande fun Anthony Obọh lẹhinti o pada lati Ghana Jakande si sọ fun un pe ki o lọ sinmi fun ọjọ mẹrin ni ilu rẹ Ishan.

Ọgbẹni Durand wa pe akiyesi ẹjọ ti Ọgbẹni Obọh ro ni Ile ẹjọ pe, pọnun mẹwa (£10) ni on gba n i g b a t i nwọn si ran on lọ si Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, ṣugbọn on kọ lati lọ si Ipinlẹ na nitoripe on ko gbọ ede Ibo.

Lẹhin eyi ni Ọlọla Louis Mbanefo ọkan ninu awọn A d a j ọ Agba bere pe, "tani o san owo na fun wọn? Ṣugbọn Ọ g b ẹ n i Durand dahun pe, "Iwe na ko sọ pato" Lẹhin idahun rẹ yi, Ọlọla Mbanefo fi jiji rẹ bọ oju, o si kọ nkan sinu iwe rẹ o si sọ fun Durand pe, "Ma a ba ọrọ rẹ nso."

Ọgbẹni Durand wa pe akiyesi awọn adajọ si ọrọ ti Henry Oleari sọ niwaju adajọ Ṣowẹmimọ pe on ko de ile oloye Awolọwọ ni nọmba 7, Bell Avenue Ikoyi nigbati nwọn fi ofin pajawiri gbe oloye na.

Nigbati o pari ọrọ rẹ lori Ọbọh ati Oleari ni o wa fi abọ si ori Ọgbẹni Patrick Dokotri, ọkan ninu awọn asiwaju ẹgbẹ UMBC ni Ipinlẹ Ariwa.

O ni ẹri ti Dokotri jẹ niwaju adajọ fi han ẹnikẹni pe Dokotri ki iṣe ẹlẹri ododo ẹri rẹ ko si to tẹle bi enia ko ba fẹ ṣina.

O ni Ọgbẹni Dokotri sọ niwaju Adajọ pe, on wa ninu Ipade kan ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ni Ibadan ni ọjọ kọkanlelogun oṣu kọkanla ọdun 1961.

O ni Dokotri sọ pe ninu ipade na ni awọn ti yan enia ti yio lọ si Ghana fun ẹkọṣẹ "Ogun" ṣugbọn o sọ niwaju adajọ na ni opin ọrọ rẹ pe, Oloye Awolọwọ ko si ninu ipade na.

"Nigbati Dokotri sọ pe on wa si Ibadan yi, ni asiko na ni o wa ni Ipinlẹ Ariwa ti o npolowo Ibo atundi si Ile Igbimọ Ipinlẹ na nigbati Ọgbẹni Richard Babalọla sọ ninu ọrọ rẹ, Dokotri gba pe, on wa ni Ipinlẹ Sadauna ni asiko na ki isi ṣe Ibadan ni on wa gẹgẹbi on ti ṣe rọjọ niwaju adajọ" O wa sọ pe, O ṣe ẹnikẹni lenu lori ọrọ ti Dokotri sọ ni adajọ ki o ṣe idajọ rẹ.



Ọgbẹni Adebiyi

(Wo oju ewe kẹfa)

# Ẹniti O Sọ Ẹlẹdẹ L'Ekurọ Ore Nla Lo Se Fun Un

OLOTU gba mi laye ninu iwe Irohin rẹ lati fi itan kekere yi jomitoro ọrọ ti ngo sọ, gbogbo wa ni a ti mọ wipe; "Isasun ti yio ba jẹ ata idi rẹ yio gbona" ati wipe "Ẹnikẹni ti o ba fi ibinu sọ ẹlẹdẹ ni ekurọ, ore nla lo ṣe fun ue. Toto, owe ẹnyin agbalagba ni o.

## Lati Ọwọ Ẹrukobodo Eko

Itan mi na lọ bayi:- Ni igba iwaṣẹ, ọkunrin kan ni Aja kan, Ọlọrun da Aja yi ni abami, nitoripe, Ọlorun fun Aja na l'agbara lati ma sọrọ gẹgẹbi enia.

Ni ọjọ kan, Olowo Aja yi ko si nle, awọn ọmọ, Olowo rẹ mejeji bẹrẹ si ja, nigbati nwọn jija na tan Aja yi pe awọn mejeji, osi pari ija na fun wọn, nigbati o pẹ ti Aja yi ti nṣe bẹ, ọrọ na han si awọn ara ile, nwọn si ṣofofo ọrọ na fun Olowo Aja na, ṣugbọn, Olowo Aja yi ko gba wọn gbọ.

Ni ọjọ ti Olowo Aja yi yio mọ wipe Aja on nsọrọ, ni ọjọ ti o tun Aja rẹ na lọ sile ọrẹ rẹ, nigbati o ku si dẹdẹ ki nwọn dele ọrẹ rẹ, ni o gbọ ariwo ija, nigbati on ati Aja rẹ wọle nwọn ba iyawo ọrẹ rẹ meji l'ori ija, ọkunrin Alaja yi, bere ohun to fadi ija, a w ọ n mejeji rojọ, njeri ọkunrin yi gbe ẹnu lati pari ija na, ni Aja rẹ ba bọ sarin wọn, o da ẹbi fun ẹlẹbi, o da are fun alare. Nigbati Aja yi ti bẹrẹ si sọrọ, ni arẹ ti mu ọkunrin Alaja yi depo, ti ko tun le sọrọ mọ, ẹnu Aja rẹ lo bẹrẹsi wo. Ọrọyi jẹ iyalẹnu fun Alaja ati ero iworan

BI SOBIA YIO BA D'EGBO OLUGBANBẸ L'AKESI

Kini Aja yi soro tan si ọkunrin yi ko s'opo ṣe meji ilẹ ọba ilu lo mu u lọ nigbati o de ọdọ ọba, o sọ fun Ọba wipe, Kabiesi! O h u n iyelẹnu kanni mo wa fi han yi, nwọn ti nsọ fun mi wipe Aja mi yi nsọrọ gẹgẹbi enia nko gba wọn gbọ, ṣugbọn loni yi, o sọrọ ti mo fi eti ara mi gbọ, ki isi ṣe etc, ki nbo itu ohun bayi mọra nitoripe, ẹnyin agbalagba lo ma npa l'owo wipe "Bi sobia yio ba di egbo, Olugannbe laa kesi". Ki owe na jẹ ti nyin.

Nigbati ọba gbọ bẹ, o ki gbe to o, o pe awọn Iranṣẹ rẹ, nigbati awọn Iranṣẹ de, ọba ni ki ọkunrin yi tun sọ ohun to sọ fun on, ọkunrin na sisọ ọ gẹgẹbi o ti ṣe sọ fun Ọba fun awọn Iranṣẹ Ọba na ati wipe ọkunrin yi sọ fun Ọba wipe, on le jẹki Aja na sọrọ ki Ọba gbọ, Ọba da a lohun wipe rara o, ki iṣe on ati awọn Iranṣẹ on ni yio gbọ Aja, biko ṣe gbogbo awọn ara ilu Ọba sọ fun Alaja na wipe:- Ma a mu Aja rẹ lọ, bi o ba di ọjọ marun ki o tun mu pada wa.

Lẹhiu ti Alaja nu Aja rẹ lọ tan, ọba ran awọn Iranṣẹ rẹ wipe, ki nwọn o lọ lu agogo fuu ara ilu wipe ni ọjọ maruu loni, ki ẹsẹ t'ọmọde t'agba. ko pe si Afin. Ki ilẹ ọjọ karun o to mọ ọkunrin yi ti mu Aja rẹ de Afin ati wipe ẹniti ko le rin ninu ara ilu ni ki nwọn o gbe on de Afin.

Nigbati ẹsẹ t'ọmọde t'agba pe sinu afin, ọba pe ọkunrin Alaja yi, o sọ fun wipe, ki o mu Aja re yọ si gbangba, nigbati o mu Aja rẹ sode tan, o sọ fun Ọba wipe, on nfẹ ki ọba mu awọn ọdaran meji, ki nwọn o wa rojọ, bi nwọn ba rojọ tan ki ọba jẹki Aja on pari ja na.

Ọba sọ fun Alaja na wipe ti ẹniti yio rojọ ko to nkan ohun ti on Ọba fẹ sọ fun iwọ Alaja yi ni wipe enia ki wa purọ niwaju on bi on ba fi enia sode, ti nwọn ba rojọ, ti Aja rẹ ko ba da ẹjọ na on yio sọ fun awọn Iranṣẹ on ki nwọn o sun ọkunrin na ṣugbọn bi aja ba sọtọ tabi bi o ba pari ija na on yio sọ iwọ Alaja na di Oloye kan pataki ati wipe, on yio da ile on ọna on meji on yio fi da ọ lọla Ọba tun bere lọwọ alaja na wipe ṣe ohun ti sọ sọ yi ti o lọrun, Alaja na da Ọba lohun pe, o tẹ on lọrun bẹẹ

Lẹsẹkẹsẹ, Ọba pe awọn Ọdaran meji, o ni ki nwọn ro ohun to gbe wọn de Itimọle, o si tun sọ fun Alajẹ wipe, ki o mu Aja rẹ lọ si ori Akete-Idajọ, Aja g'ori Aga idajọ, o joko tente.

Wo Oju Ewe Karun

## Ẹ Ba Ọlọmọ Yọ Ṣẹṣẹ

Lẹnulọlọ yi ni a sọ fun ẹnyin onkawe wa wipe Ọlọrun fi ọmọkunrin kan t a. Ọbabinrin Gẹẹsi Ọlọlajulọ Elizabeth keji ati ọkọ rẹ Ọlọla Duke Edinburgh r ọrẹ



Ninu aworan oke yi, eo ri ọmọ titun na ti awọn ẹbi Ọbabinrin na nwo ninn itẹ rẹ, nibiti o dubulẹ. Ọbabinrin Elizabeht keji, ọkọ rẹ pẹlu awọn ọmọ rẹ ni nwọn duro ti ọmọ titun na ninu iwe yi. Ki Ọlọrun ki o da ọmọ na si, ki Ọ b a ki o pẹ titi o, amin.

# IWE SI OLOTU

## Ọyọ Nfẹ Atunṣe Ijọba

Olotu, inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati kesi awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati le ba wa ṣe atunṣe ọpọlọpọ awọn oju ọna to wọ arin ilu Ọyọ, ọpọlọpọ awọn ọna wọnyi ni ọda ti wọn da si ọna na ti kuro ti awọn Ijọba ko si ṣe atunṣe awọn oju ọna wọnyi.

Eleyi si mu ipalara wa fun awọn onimọto to nrin awọn oju ona wọnyi papajulọ, awọn to ngun basikulu.

Inu wa yio dun bi Ijọba Ibile Ọyọ ba le ṣe itoju awọn ona wọnyi ati pe yio tun mu anfani wa si ilu Ọyọ fun awọn ọpọlọpọ ọja to yẹ ki o wọ ilu na yio ma a ni aye lati wọ arin ilu wa ra ọja.

Mo dupẹ o, Olotu.

Emi ni,
ANTHONY ỌRẸKỌYA,
ỌYỌ.

Ti nwọn ba le ma lọ kakiri awọn na yio le mọ awọn ohun ti ilẹ wa nfẹ fun ilọsiwaju

Mo dupẹ lọwọ rẹ, Olotu.

Emi ni,
ỌLA LADELE
Igbẹti

## Ẹla Eyi Ye Mi

Inu mi yio dun pupọ bi olotu iwe Irohin Imọle ba le gba mi ni aye lati bere Ọrọ mi ti lọdọ awọn Ọjọgbọn ati Oloye yi nka iwe nyin nigba gbogbo.

Ọrọ mi na lọ bayi:- Awọn Omode meji kan wa ti nwọn fẹran arawon, nwọn gbe papọ, nwọn jijọ da owo jọ lati fi ra epo Oyinbo sinu apo ti nwọn jọ nlo

Ọkan ninu wọn ra erọ idana ti o je Sitofu o si ra epo ti ero idana loto sugbọn ti o ba ti lo epo tirẹ, o tun nji epo ti nwọn jijọ ra lati ma fi tan na lo.

O wa di Ojọ kan bi o ti fe ji epo yi bu ẹnikeji rẹ ba ri o ni ha! aṣe iwọ lo njẹ ki epo wa tete tan. Bi o ba to sitofu lo, kini ṣe ti o ma lo igi bi temi? kaka ki o bẹbẹ oni ki o ṣe ife nu re.

Ẹjọ wọ kini ki ẹnikeji ṣe? se ki nwọn ma jijọ ra epo pọ ma ni? koye mi.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi Ọlọrun yio bo aṣiri amin o.

Emi ni
M. A. ARANSIỌ
Oshogbo

## Jagun Jagun Wọlu?

Inu mi yio dun sẹsẹ ti ẹ ba le ba mi tẹ Iwe mi yi jade fun gbogbo awọn onkawe Irohin nyin ka.

Iya lẹnu ela ni ọrọ yi jẹ fun gbogbo ọmọ Ilesha ni ọjọ aiku ti ise ọjọ karun osu yi nigbati awọn olori ẹgbẹ Demọ ko awọn janduku ẹgbẹ wọn de arin ilu ti nwọn si bẹrẹ si lu wa kiri lai ja ti tele.

Ọrọ yi je ijọju fun gbogbo enia ti o ti lẹ fẹ lọ gbọ ọrọ ti nwọn fe ba wa sọ.

Bi o ba ie wipe bi awọn ẹgbẹ Demọ ti fẹ ṣe wa ni yi yio dara fun awa ọmọ Ijesha ti a ba tete jina si awọn ẹ l ẹ g b ẹ "Daluru" wọn yi

Mo dupẹ lọwọ nyin olotu mi ọwọn. Ọwọ nyin yio ma roke o.

Emi ni
James Ogedegbe
Ilesha

## Ẹ Gba Eyi Yẹwo

Ayọ nla ni yio je fun mi ti e ba le tẹ iwe mi yi jade ninu iwe Irohin nyin oloyin momọ.

Mo fe ki awọn Minisita ti nwọn nse Alakoso Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria ma ṣe abẹwo yika ilẹ wa.

Ọpọlọpọ enia ni ko mọ wọn soju, pelupelu awọn Minisita na kọ tilẹ mọ ibiti ilu miran wa tu akajuwe ninu iwe ti nwọn ri lọ!

## A dupẹ o

A dupẹ pupọ lọwọ nyin ati awọn oṣiṣẹ to wa labẹ nyin fun iwe nyin oloyinmọmọ ti a tete nri ka ni Shomolu ati Bariga nigba gbogbo.

Inu wa si tun dun pupọ fun awọn itan oloyinmọmọ ti a nri ka ninu iwe na papa julọ awọn ọrọ lati ẹnu Yẹyẹnatu to fun wa ni ọgbọn.

Awa si mọ pe Irohin Imọlẹ si ti di araba. A si tun dupẹ gidigidi lọwọ Olotu pẹlu Alakoso ile iṣẹ na fun alaye ti nwọn tun se lori iwe oloyinmọmọ na pe ko fi ara mọ ẹgbẹ Oselu kankan ati pe ọpọlọpọ enia lo si aro pe ti ẹgbe UPP ni iwe na iṣe sugbọn gbogbo enia ni eyi si ti da loju pe ki iṣe bẹ rara.

Ẹ ku iṣẹ, iwaju ni ọpa ẹbiti nyin yio ma a lesi o.

Emi ni
JOSEPH ỌRẸKỌYA
Shomolu

## Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ lojojumọ


## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igbor joko le ṣe Iwosan wọn latiai afi ki o ri ojulowo Egboo ilu ko ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibgi "Ikọ" si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹ iti oti bere fun egbogi wọnyi:

### "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asma, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ik Igbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki nia ma ha ọna ọfun tabi pelu kelẹbẹ tabi ti o ma njẹki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsana ti oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburu-gburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta ka iri

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Bere egbogi ajẹbina Richelet yini ṣọbu awọn
Waterloo Medicine Store
8, Plamchurch Street, Lagos
Phone:-2287 Nigeria, (Ọja ita Faji)



# Kere o!

Fun anifani gbogbo ẹnyin onisowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio ṣe ipolowo awọn oja nyin fun nyin ni ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin ọdun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ti ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aṣoju wa yio ma a lọ kakiri lati bere fun awọn ti o ba fe lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lekan ki o sri bi ajo re yio ti ta to. Ijafara lewu o.



AH! REMEMBER THAT

# The Social Dandies

*PRESENTS*

## An Eid-Ul-Kabir Dance
AT
FORSTER CENTENARY HALL

22, Ọdunlami Street, Lagos, On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn
*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

### Tickets: 4/- Flat

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgbose Street, I r o h i n Imọlẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Metta.

# Senghor Sọ Pe On Tigbọ Pupọ Nipa Iwọ Orun

Nigbati Arẹ ilu Seneghor ṣ ibẹwo rẹ de Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria fi Olotu Ipinlẹ na fun ni iwa nipa Ipinlẹ na were ni Arẹ na dupẹ owo rẹ ti o si sọ fun pe on ti ngbọ pupọ nipa Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Arẹ Senghor si tun ba sọ ninu ọrọ rẹ pe inu on dun pe on tun ba Olotu na sọrọ loni ati pe iwe ti o fun on yio wulo fun alaṣẹ eto nipa irohin ilu on

Arẹ na tun kan saara si awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ri pe nwọn ko gbagbe awọn nkan igbani ti awọn enia wọn.

Ọjọ nla ni o jẹ fun Arẹ na ni ọjọ ti o de Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria. Fun iki ni ku abọ si Ipinlẹ na, Oloye S. L. Akintola sọ ninu ọrọ rẹ pe Arẹ Senghor ati awọn enia rẹ ki iṣe alejo si ilẹ Naijiria rara.

Oloye Akintola sọ ninu ọrọ rẹ pe, iru ibẹwo yi fun Olori kan ni ilẹ Afrika yio mu iṣọkan ati irẹpọ wa fun ilẹ na ati papajulọ fun awọn enia ilẹ Afrika.

Gẹgẹbi Arẹ na ṣe nde si Ebute-ọkọ ofurufu ni Ibadan ni Gomina Ipinlẹ na Oloye Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi mu ṣe ayẹwo awọn ọmọ Ogun ti ilẹ Naijiria.

Lẹhinna ni nwọn si kuro ni Ebute ọkọ ofurufu ti mu Arẹ na lọ si papa iṣere ti (Liberty Stadium) Nigba ti Arẹ na ri papa iṣere na o kan saara si Ijọba Ipinlẹ na ati pe Arẹ na si tun sọ pe papa iṣere na jẹ nkan ayẹwo fun ilẹ Afrika.

Lẹhin eyi, Arẹ na si tun ṣe ayẹwo Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ na.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Gbogbo rogbodiyan ti o ba kọlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ yio fo ọ kọja, larin ọsẹ yi iwọ nikan ni yio si ku.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Iṣoro kan yio de ba ọ larin ọsẹ yi ṣugbọn iwọ yio ri ara gba gbogbo rẹ si ju awọn yoku rẹ lọ.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ki ẹnu maṣe ya ọ fun ohun kohun ti o ba nṣẹlẹ si ọ larin ọsẹ yi. ohun pataki kan ni o nṣẹlẹ si irawọ rẹ.

TAURUS (April 21 - May 20) Ẹru le ba ọ diẹ fun ọrọ kan ti yio ṣẹlẹ, ṣugbọn irawọ rẹ dara owo pẹpẹpẹ yio tẹ ọ lọwọ larin ọsẹ yi.

GEMINI (May 21-June 21) Bi o ti jẹ pe aye wa fun ọ lati ronu ninu ọsẹ ti kọja yi lori ohun pataki kan gbiyanju lati ri pe, o mu ohun pataki kan ṣe nipa rẹ.

GANCER (June 22 - July 23) Ṣọra rẹ pupọ larin ọsẹ yi ki ibi ma a ba de ba ọ lati orişirişi ọna. Iwọ yio bori iṣoro na bi o ba ni ọpọlọpọ suru.

LEO (July 24 - Aug. 22) Iyipada nlanla yio bẹre ninu igbesi aiye rẹ. Ohun iyanu ni yio si ma a ṣẹlẹ nigbagbogbo si ọ

VIRGO (Aug. 23 - Sept.) Ọlọrun ti fun ọ ni eto ṣiṣẹ, nitorina lo ẹbun yi lati ma a tun ọna rẹ ṣe larin ọsẹ yi.

LIBRA (Sept. 24-Oct. 23) Lọ ni ọpọlọpọ suuru ninu ọsẹ yi ki o ma ba padanu ire kan ti mbọ wa fun o, maṣe kanju ti ko ba tẹ ọ lọwọ ninu ọsẹ yi, o nbọ lọna.

SCORPIO (Oct. 24 - Nov. 23) Awọn enia kan yio ṣe alagbọwọ fun ọ larin ọsẹ yi, nitorina lọ ni ọpọlọpọ suuru ki anfani na ma ba fo ọ kọja.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec. 22) Oju gbogbo enia ni yio wa lara rẹ lẹnulọlọ yi, bi o fẹ bi o kọ ọ.

CAPRICORN (Dec 23 - Jan. 21) Ẹnikan fẹ si ọ lọna, nitorina maṣe kẹgbẹ, ki o ma ba gbe onjẹ alẹ rẹ fun ologbo jẹ.


# Gbanjo o !

Eyi ni lati kedefun gbogbo awn ONIBARA wakọ jake jado agbaiye pe ao bẹrẹsi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:–

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome** ati **Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tete bẹrẹ GBANJO na

TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 28th MAR.–30th APR

Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6d
Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu ṣiṣe 21/- di 18/-
Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba Psalm Iṣẹgun Ajẹ 4/6d di 3/-
Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d
Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6- di 2/-
Turari Iṣẹgun Ajẹ 10/6 di 8/-
Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-
Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d
Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-
Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-

AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

Shoyinka
N2/99 Shittu Street
Ibadan



# EGBOGI JẸDIJẸDI

FUN EGBOGI



## "CYCLOVE"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Ihoidi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amod ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ ade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVE" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ a ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi na pata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taagboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street Yaba — Lagos

## Eniti o Sọ Elẹdẹ Ni Ekurọ Ore Nla Lo Ṣe Fun un

Lati Oju Ewe Keji

Nigbati awọn ọdaran mejeji rojọ tan, njẹ ki Aja da ohun ti nwọn ro, ọrọ di womi nwo ẹ, bi o karan ki Aja sọrọ, ori lo ini pẹkẹ pẹkẹ lori aga to joko si, nigbati ọrọ na ka Alaja lara o sunmọ Aja rẹ obẹrẹ si kigbe mọ wipe Sọrọ! Sọrọ!! Sọrọ kẹ!!! Aja kọ jalẹ ko sọrọ. Nigbati Alaja rii wipe Aja ko sọrọ jinni-jinni ku mu u, o bẹrẹsi gbọn, Nigbati Ọba ri wipe Aja ko sọrọ, o paṣẹ fun awọn Iranṣẹ rẹ wipe, ki nwọn lọ sun Alaja na nina, Gbogbo igbati awọn Iranṣẹ nlọ dana Aja nwo wọn, nwọn dana tan, nwọn fẹ gbe Alaja si i, o nwo wọn nigbati nwọn fẹ gbe Alaja sina. Ọba sọ fun awọn Iranṣẹ rẹ wipe:- Ẹmaṣe ju sina na lẹkan, mo fẹ ki ẹ kọkọ fi ẹhin rẹ rana, ki ẹ un fi ẹgbẹ rẹ rana, bi o ta di ẹlẹkẹta niki ẹ to ju sinu ina.

Awọn Iranṣẹ ki Alaja ti mọlẹ, n w ọ n so o loku, l'apa-l'ẹsẹ, n w ọ n gbee. Nwọn kọkọ fi ẹhin rẹ rana aja nwo wọn, nwọn tun gbe, nwọn fi ẹgbẹ rẹ rana, Aja nwo wọn, nigba ti o d ẹlẹkẹta, bi nwọn ti fẹ gbe e j u sinu ina Aja sọrọ o ni Kere! Kere!! Kere o!!

Nigbati Aja sọrọ gbogbo ero nworan bẹrẹsi kigbe wipe, Aja sọrọ! Aja sọrọ!! Ọba paapa s ọ fun nwọn Iranṣẹ rẹ wipe:- Ẹgbe silẹ, ẹ maṣe j u sinu i n a mọ, ṣugbọn, k nwọn o to gbe, silẹ gbogbo ara rẹ lo t i ta ipẹpẹ ati wipe, oju rẹ, si ranko bi oju were

Nigbati Aja r i i wipe Olowo on ti fi ara ra ina tan, ọ r ọ to sọ ni pe, Kabiesi! Nitotọ ni Ọlọrun d a mi ni Aja, o si fi ọrọ sisọ gẹgẹ bi ti enia simi lenu, ohun ti ko jẹki nkọkọ sọrọ gbolohun ti Ọba kọkọ sọ fun Olowo mi ti o sọ wipe bi nko ba sọrọ on ju Olowo mi sinu ina, ati pe, bi mo ba sọrọ' on yin sọdi Oloye ati pe on d a iln o n ọna rẹ si meji on y i o fi d a Olowo mi lọla titi di ọjọ ku rẹ, bẹni, mo fẹran Olowo mi pupọ, ohun ti mo ṣe fun olowo mi yi, o dabi ẹni pe, mo fi iya jẹ ni, ṣugbọn mo m a lọkan ara mi wipe ore n l a ni mo ṣe fun un, nitori p e, bi mo b a tete s ọ r ọ, bi Ọba ba ba ile on ọna rẹ si meji, ti o koo fun un, ti o tun sọdiOloyin ati Ọlọla, bi o ba de ori ọla na tan i ṣe k u ṣ e ni yio ma a ṣe nitori p e, k o ṣ e wahala kan ki ọla na o to tẹlọwọ, nipa iṣe kuṣe rẹ lori ọlana. ọla na l e ti bẹ b ọ kuro lọwọ rẹ.

L'ọna keji, bi o ba de ori ọla na, ni alai ko jẹ wipe, o fi oju ri ina aiye bayi, koni mọ iyi ohnn ti on Aja ṣe fun un, ki ọla na o to tẹ ẹ lọwọ.

Lẹhin ti Aja sọ bẹ ẹ tan, Ọba da ile ati ọna rẹ si meji o ko fun Alaja na, o si tun ṣe ni Oloye kan pataki larin ilu na; eyi ni ohun ti awọn baba nla wa ri ni ọjọ kini, ki nwọn o to sọ di owe wipe:- Iṣasun ti yio jẹ ata, idi rẹ yio gbona.

## Ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre Mushin Ati Agbegbe Rẹ Yan Oloye Titun

Ninu ipade ti Ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre Mushin ati agbegbe rẹ ṣe ni ọjọ karun oṣu kẹrin ọdun yi n i Road House Hotel Idi-Oro ni agogo meji ọsan. Ẹgbẹ ra yan awọn Oloye, titun wọn yi.

1. Aalga Ọgbẹni O. Abayomi, 2. Igbakeji Ọgbẹni A. Amọdu, 3. Akowe Ọgbẹni I. Alebiosu, (4) Igbakeji akọwe A. Ọnatolu (5) Akọwe eto Ọgbẹni A. Tella, (6) A k ọ w e owo Ọgbẹni R. Sanni, (7) Akapo Ọgbẹni M. A. Akosilẹ, (8) Ayẹ iwe owo wo Ọgbẹni S. O. Salami (9) Atẹwe ẹgbẹ Ọgbẹni T. Becfroft, (10) Alamojuto owo ẹgbẹ Ọgbẹni Rashidi Musa (11) Akọwe gbajumọ (12) Onidajọ ẹgbẹ Ọgbẹni J. Kojẹku, (13) Igbakeji rẹ; Ọgbẹni M. Abiodun (14) Oludamọran ẹgbẹ Ọgbẹni A. Mọsanya (15) A k ọ w e Ipolowo ẹgbẹ Ọgbẹni O. Savage.


B O BA NI

# Iwe—Titẹ

UN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*



# Kere o

10TH BOOK OF MOSES: Iwe kẹwa Mose, Iranlọwọ nla fun awọn Ẹgbẹ Aladura lọna iwaa-j ifihan, asọtẹlẹ. Aṣiri imularada lọna oriṣiriṣi, aṣiri isọ agan di ọlọmọ, igba ni lọwọ awọn agbaalagba. Agbojọ, ki a wi bẹ ẹ ki o si ri bẹẹ lọnaka, mayehun atata. Pọnun kan (£1) pere. A le ri i ra lọ dọ MANAGER 15, Araoti Street, Yaba-Nigeria ati ni ọdọ awọn wọnyi: Abudu Akangbe, Ile Tabintin, Ikire via Ibadan, David Taiw., 19, Ajegunlẹ Street, Ilupeju, Mushin ati Thomas A k i n k u n m i, c/o- Dr Ayọ Alade, Oke Elerin, Ogbomọsho.



## Congreve's Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi aamodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ekọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba

Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju llaogun ara ẹṣẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati oriṣiriṣi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Oriṣiriṣi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu iko iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egboogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ila-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati oriṣiriṣi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone: 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

